# Ṣíṣàtìlẹ́yìn fún àwọn ọmọ ilé-ìwé tóní àìléra Tourette Syndrome àti àwon àìṣedéédé Tîîkì



Àpò irin iṣẹ́ ni a piyamọ rẹ̀ láti ran àwọn olùkọ́ni lọ́wọ́ àti láti ṣàtìlẹ́yìn fún àwọn òṣìṣẹ́ nínú dídá àwọn àmì tó lágbára mọ̀ àti láti dúró gẹ́gẹ́bí ìtọ́nisọ́nà sí ṣíṣe ètò ìrànwọ́ tó múnádóko láti leè gba àwọn ọmọdé tó ní àìléra Tourette Syndrome àti àwọn àìṣedéédé Tîîkì láàyè láti gbìyànjú ìlàkàkà wọn láwùjọ àti ní bi ètò ẹ̀kọ́ wọn. Àpò irin iṣẹ́ ni óùn pèsè fún àwọn olùkọ́, àwọn alábòójútó, àwọn olùdámọ̀ràn, afiṣemọ̀rònú ti ilé-ìwé, àwọn olùdámọ̀ràn lórí iṣẹ́ àti ìsọ̀rọ̀, àwọn nọ́ọ̀sì ilé-ìwé, àwọn ọ̀jọ̀gbọ́n ilé-ìwé àti àwọn elòmíràn tón ṣàtìléyìn láti ṣèrànwọ́ lórí níní òye àti láti sàtìlẹ́yìn pẹ̀lú áwọn ọmọdé to ní àmi TS àti àwon àìṣedéédé Tîîkì.

Àmi TS àti àwon àìṣedéédé Tîîkì n bá àwọn ọgọ́rùn-ún (100) ọmọ ilé-ìwé fínra. Tóju ìdajì àwọn ọmọ tí ọjọ́ ori wọn bàti ilé-ìwé muní àmì TS ti leè wà ní ipò àtúnwá ìṣẹ̀lẹ̀ tó maà n ṣẹlẹ̀ lórèèkóòrè bíi ADHD, OCD, àníyàn, ìrẹ̀wẹ̀sìì ọkàn tàbí ìṣòrò ìkòwé. Àwọn ipò yìí pẹ̀lú àwọn ìṣòro ẹ̀kọ́ kíkọ́ míràn, leè ṣ'àkóbá fún ẹ̀kó kíkọ́ lọ̀nà tó gbà lòdì, tó sì n jẹ́ kóle fún àwọn ọmọ ilé-ìwé làti f'ọkàn sí nkàn tí wọn n kọ́ nínú kíláàsìì.

Àjọ Tourette ti ìlú amẹ́ríkà (TAA) pèsè fún àwọn olùkọ́ni pẹ̀lú àlàáyé láti dáá àmì TS àti àwọn àìsedéédé míràn tó jọ ara wọn mọ̀. Ó lágbàra fún àwọn olùkọ́ni, òbí àti àwọn akẹ́kọ̀ọ́ láti fọwọ́sowọ́pọ̀ nínú ṣíṣe àgbékalẹ̀ àwọn ibùgbé tó múnádóko láti ṣèrànwọ́ fún ìrọ̀rùn ẹ̀kọ́ kíkọ́ fún gbogbo ọmọ ilè-ìwé. Tí abá ṣe àgbéyẹ̀wò tí a sì sọ̀rọ̀ lórí àwọn àmì TS àti àwọn àìsedéédé míràn tó jọ ara wọn, àwọn ọmọ ilé-ìwé leè ní àwọn ìrírí ìlé-ẹ̀kọ́ tó pegedé.

1/100

**Ó kéré tan, ọ̀kan (1) ninu ọgọrun (100) awọn ọmọde ní àìléra Tourette Syndrome tabi tîîkì.**

**Àjọ Tourette**
Tí Ìlú Amerík̀à
Ìtanilólobó. Ìwádìí. Àtìlẹ́yìn.

42-40 Bell Blvd., Suite 205, Bayside, NY 11361 **Tourette.org 888-4TOURET**

7__ToolKit12pagerEducatorFinal2020_YO.indd 1 6/9/2022 3:07:41 p. m.

## BÍ A ṢELE HÙWÀ SÍ ÀÌLÉRA ÀRÙN TOURETTE ÀTI ÀWỌN ÀÌṢEDÉÉDÉ TÎÌKÌ NÍ ÌYÀRÁ ÌKẸ́KỌ̀Ọ́

Òfin àkọ́kọ́ fún ọ̀pọ̀ àìṣedéédé tîìkì ní kí o pawọ́ntì pátápátá. Ànfààní tó wà nínú pípa àwọn tîìkì tì nìwọ̀nyìí:

- Dín wàhálà àti àníyàn fún àwọn ọmọdé kú, eléyìí tí àbájáde rẹ lè b'àwọn lẹ́rù tàbí b'àwọn Lójú jẹ́.
- Dín wàhálà àti àníyàn fún àwọn ọmọdé kú, eléyìí o leè mú àdínkù bá àwọn ààmì.
- Dín ìwà ìréjẹ kù.
- Fí ìwà ìkónimọ́ra hàn àti kí o sì rí àwọn àmì yìí gẹ́gẹ́ bí tó tún ṣelẹ̀ lemọ́lemọ́.
- Àwọn ìwà tótọ́ tó sì tún dára láwùjọ fún àwọn ọmọdé ilé ẹ̀kọ́.



## DÍDÁ ÀWỌN ÌṢÒRO ÉKỌ́ TÓ WỌ́PỌ̀ PẸ̀LÚ ÀÌLÉRA TOURETTE SYNDROME MỌ̀

Àwọn olùkọ́ni àti àwọn ẹbí gbọ́dọ̀ ṣọ́ra fún àwọn ìpènijà tó wọ́pọ̀ tí ó leè pa ìṣesí àwọn ọmọdé tó ní TS yìí ní ilé ẹ̀kọ́ lára. Nígbà míràn àwọn ìpènijà ní a máa n ṣì túmọ̀ tàbí ronú nípa "àwọn ìwà tó ní àfojúsùn" Dípò àwọn ìṣòro tó le eléyìí to je wípé àìsedéédé ìdàgbàsókè ọpọlọ òun lo sokùnfàá.

Ìṣòro ètò ẹ̀kọ́ ọ́ún dígbà fi lójú síi ní àwùjọ ilé ìwé gíga.

Àwọn àtòkọ yìí ní o ṣọ̀rọ̀ nípa àwọn ìṣòro tó jẹ mọ́ ilé ìwé tí àwọn ọmọ ilé ìwé pẹ̀lú TS àti àwọn ipò míràn to lè wà níbè eléyìí to wọ́pọ̀.

- **Ìṣòro pẹ̀lú ìyípadà:** Ìṣòro pẹ̀lú ìyípadà láàrin àwọn iṣẹ́ ṣíṣe àti iyàrá ìkẹ́kọ̀ọ́; Lílọ́ra sì ìyípadà nínú ètò àti/tàbí ojúṣe.
- **Ìṣòro píparí is àmúrelé:** Ìkùnà Láti ní òye iṣẹ́ àmúrelé; àìsedéédé nínú kíkọ àwọn iṣẹ́ àmúrelé sílẹ̀; àìparí àwọn iṣẹ́ àmúrelé lásìkò; ìkùnà láti bẹ̀ẹ̀rẹ̀ àwọn iṣẹ́ àmúrelé.
- **Ìṣòro títẹ̀lé ìtọ́sọ́nà:** Lílọ́ra láti dáhùn; àìlè parí iṣẹ́ ṣíṣe eléyìí tóní ìtọ́sọ́nà púpọ̀; àwọn ìbéèrè tí à n bèèrè nígbàkúgbà fún àwọn ìtọ́sọ́nà.
- **Ìjà láàrín èsì ọ̀rọ̀ sísọ àti èsì ipa kíkọ:** Ìyatọ̀ láàrín èsì lórí àwọn àyẹ̀wò ẹ̀kọ́ nípa ọpọlọ (fún àpẹẹrẹ- ìdá nínú ọgọ́rùn ipa fún ìka ìwé, pẹ̀lú ìdá nínú ọgọ́rùn tó kéré fún ìmọ̀ ìwé kíkọ; èsì gígá nínú ọ̀rọ̀ sísọ àti èsì tó kéré púpọ̀ nínú ipa kíkó).

**Àwọn ìṣòro ètò ẹ̀kọ́ ní wọ́n máa dígbà di mímọ ní ààrín àti ilé ìwé gíga. Ìdí tó wọ́pọ̀ kàn, ṣùgbọ́n a kò dáamọ̀ rárá ní ipá ìròrí ọmọ ilé ìwé kan lè dàbí àmì ní ilé ìwé alákọ̀ọ́bẹ̀rẹ̀; ní àwọn kíláásìì tó ga, àwọn àmì ní o máa bẹ̀ẹ̀rẹ̀ pẹ̀lú dídá síí àti pẹ̀lú lí leè ṣe àfihàn ipá ìròrí tòótọ́ Ní àfikún, àwọn ọmọ ilé ìwé tó dàgbà ní wọ́n máa n dígbà fi agbára kún láti lè ṣe àdínkù tàbí ṣe awọn àmì náà pamọ́ fún ìtẹ́wọ́gbà láwùjọ.**

- **Ìdàrú ẹgbé àti àwọn àléèbù àlabòjutó tón ṣiṣẹ́:** Ìṣòro nínú ṣíṣọ̀ àkókò lo, àwọn iṣẹ́ ṣíṣe àti ohun-ìní; ìṣòro nínú bíbẹ̀rẹ̀ àti/tàbí títẹ̀le lórí àwọn íṣẹ́ ṣíṣe náà, tí o lè jásí ìkùnà láti gbé ọjà jáde.
- **ìṣòrò ẹ̀kọ́ kíkọ́ (ìṣòro ìkọ̀wé):** Lílọ́ra, pípa nkàn rẹ́ lóòrèkóòrè; ìmọ̀lára kíkọ iṣẹ́ ní mímọ́ tónítóní; ìṣèṣí tó kéré jọjọ; ìlọ́ra ìkọ̀wé; ìṣòro fífi àmì sí gbólóhùn, kíkà, àti kíkọ àwọn álfábẹ́tìì nlá; kíkọ̀ jálẹ̀ láti kọ̀wé.
- **Àìnídìwọ́ọ́:** Àwọn ìwà tí àwọn ọmọ ilé-ìwé dámọ̀ gẹ́gẹ́bí ìwà àìtọ́ tàbí èyí tí à gbégi le, sùgbọ́n ní ìṣòro nínú ìgbaniláàyè. Àwọn àpẹẹrẹ kan ni kí á ma fọwọ́ kan àwọn nkàn, sísọ àwọn ọ̀rọ̀ kógbàkògbé síbẹ̀ tó mọ́gbọ́n wa tàbí àwọn ìhùwàsí àti fífi ariwo dáhùn àwọn ìbéèrè.
- **Àwọn ìwà tó bú jáde bí àdó olóró ní ilé ìwé tàbí ilé:** Àwọn ìwà tó da tíkò sì tún bófin mu, èléyìí tófi hàn wípé ìhùwàsí tàbí ìkọbiara sí ipò náà pọ̀jù, tí o sìlè jẹ́ èsì àmì àkìmọ́lẹ̀. Àwọn ìwà mí jẹ́ nínú àníyàn tó pọ̀ jọjọ, ìmọ̀lára àṣetì, ìṣòro ìnú ọpọlọ, dídásí àwọn àmì, tàbí àwọn àléèbù ìmọ̀.
- **Ṣíṣe ǹkan lójijì:** Fífi àwọn ìwà àìròtẹ́lẹ̀ hàn, bíi pípariwo, fífẹ̀fun tàbí kíké mọ́ àwọn ìyókù.
- **Àwọn ìwá tón takò:** Àìṣedéédé nínú àìkọ̀jálẹ̀ láti tèlé àwọn ìlànà tàbí ṣe nínú iṣẹ́ ṣíṣe tàbí ìtọ́sọ́nà. Ó ṣe kóko láti roo ìwà alátakò gẹ́gẹ́bí ọ̀nà láti bá ara ẹni sọ̀rọ̀ àléèbù ìmọ̀, tàbí gìrì kàn tíkò ní ìjánu, àníyǹ tàbí ohun tí ọpọlọ nílò. Ìwò yíi ni yóò gba àwọn ìmọ̀ ètò ìdánilékòó tó múná dóko Dípò ìfiyàjeni tí kò ní àpá kan kan.
- **Fífi etí sílẹ̀:** Tîìkì tàbí àìníjànu ó leè pá ìfiyèsí lára, bí ó ti lo jẹ́ pé akẹ́kọ̀ọ́ náà f'iyè sí nkàn tón ṣe. Síbẹ̀síbẹ̀, ìdàkejì rẹ̀ leè jẹ́ òtítọ́. Àwọn akẹ́kọ̀ọ́ kàn ní anfààní ní láti lọsí àwọn ètò nígbàtí wọn ni ìrírí àwọn àìsedéédé tîìkí Lọ́wọ́, ó tún leè gbà ọ̀nà Míràn yọ.



7__ToolKit12pagerEducatorFinal2020_YO.indd 2 6/9/2022 3:07:41 p. m.

- **Ìṣerégí:** Pípàrẹ́; Àwọn nkàn tí jẹ́ wípé àgbọdọ̀ ní ni “oun tótọ́”, ṣí ṣọ́ra gidigan lórí àwọn òfin; pipáni dandan lórí ṣí ṣe àwọn ojúṣe kan.
- **Ìṣòro ọpọlọ:** Ìmọ̀lára sí iná, ìró, ìfọwọ́kàn, òórùn tàbí àwọn ìtọ́wò; ìlò fún àwọn ìfọwọ́sí ìmọ̀lára, tí ó máa fi ẹ̀kọ̀kan jásí kí èèyàn ṣe ara rẹ̀ léṣe; ìwúlò láti fí ara oun tí óún fà ìmọ̀lára balẹ̀, nípasẹ̀ jíjẹ àwọn nkàn gbígbá ara ẹni, kíkọlù Àwọn nkàn, dídì mi ara ẹni pẹ́kí pẹ́kí àti bẹ̀ẹ̀bẹ̀ẹ̀ lọ.
- **Àwọn àlébù ìbáraẹnisọ̀rọ̀ láwùjọ:** Àwọn ìwà ọmọdé: àwọn ìdáhùn tí kò dùn gba létí; àwọn ìwà tó kò dára tó láwùjọ; àìlè bá àwọn ọ̀rẹ́ ṣeré dáadáa tó.
- **Wàhálà àti àníyàn:** Ní àfikún ṣùgbọ́n tí kò tán síbẹ̀, sísá lẹ́nu ẹ̀kọ́ tàbí ní ilé ìwé; pípatì nígbàtí nkan bá súwa; ìrìn àjò tó pọ̀ jù fún àwọn nóọ̀sìì, ilé ìwẹ̀ tàbí olùdámọ̀ràn; àwọn ìké jáde lóùn rara.

## ÀKÓJỌPỌ ÀMÌ ÀÌSÀN ÌFÀRÓ IṢAN LÓJIJÌ

### Tîkì jẹ késekése nínú kàsàkàsà tó mbọ




## ÀWỌN ÈTÒ 504 ÀTI ÈTÒ Ẹ̀KỌ́ ONÍKÁLUKÚ (IEPS)

Àwọn ètò 504, bí aṣẹ júwe rè ní abala 504 nínú ìwé òfin àwọn ọmọ ìlú Amẹ́ríkà tóní àlébù (ADA), ríi dájú pé àwọn ọmọ ilé ìwé tí o ní TS ní anfàànì kàn náà sí ètò ẹ̀kọ́, àtìlẹ́yìn tí ara àti ní àwùjọ, wíwà àwọn ètò lẹ́yìn wákàtí ilé ìwé, àti ìdáàbòbò lọ́wọ́ ìpaniláyà. Àwọn akẹ́kọ̀ọ́ tóní TS ní wọ́n máa n dígbà ní anfàànì fún àwọn ètò 504 yìí nítorí pé wọn kó oju òṣùwọ̀n, ṣùgbọ́n ní àwọn àmì tí kò yèé wọn eléyìí tó n dígbà díwọn lọ́wọ́ láti nkàn tí wọ́n kójú òṣùwọ̀n láti ṣe. Àwọn ètò 504 tó wọ́pọ̀ náà ni ìlò ẹ̀rọ ayélujára, wàálà, ìkọ̀wé ìgbàlódé, tàbí ààyè láti kúrò ní ìyàrá ìkẹ́kọ̀ọ́ tí o bá ṣe kókó láti leè dín ṣí ṣàníyàn tàbí àwọn àìṣedéédé tic kù. Àwọn ilé ìgbé yìí náà ni òní àwọn ìyárá àyẹ̀wò ọ̀tọ̀ọ̀tọ̀, ibùjókòó tó yàtọ̀, wíwà nínú gbọ̀ngàn nígbàtí èrò kòsí níbẹ̀ àti àwọn iṣẹ́ àmúrulé tó dínkù jọjọ nígbàtí o bójúmú.

Nígbàtí àwọn ètò 504 kò bá péye tó, nínú bíbá àwọn ohun ìní àwọn akẹ́kọ̀ọ́ náà tí wọn ní TS, nígbà náà ní aó pa IEP ní dandan. Nígbà gbogbo, a máa n fi IEP dun àwọn akẹ́kọ̀ọ́ tóní TS nítorí èsì ìdánwò tó ga àtièsì ìdánwò tó kọjá ìdajì lórí àwọn iṣẹ́ ṣíṣe nínú ètò ẹ̀kọ́. Nígbàtí àwọn IEP bá pèsè àwọn ààbò kàn náà àti àtúnṣe/àwọn ilé ìgbé gẹ́gẹ́bí àwọn ètò 504, àwọn náà ní wọn óo tùn pèsè àwọn ètò láti ọwọ́ alátìlẹ́yìn nígbàtí àwọn tóní àlébù ìbáraẹnisọ̀rọ̀ láwùjọ nkojú àwọn ìdádúró, ìgbésókè ọpọlọ, àníyàn àti/tàbí àwọn àlébù alábòjútó tó n ṣiṣẹ́ leè dásí ètò ẹ̀kọ́ àwọn ọmọ ilé ìwé tàbí ìserere láwùjọ lọ́nà ti kò dára tó. Ní àfikún, omo ilé ìwé t'óbá ni àmì TS leè bèèrè fún àtìlẹ́yìn àwọn tí kò tîì kọ́ṣẹ́mọ́ṣẹ́ fún ìrànlọ́wọ́ nínú àwọn ìmọ̀ kàn tó yàtọ̀. Wọ́n tún leè se ìrànlọ́wọ́ nínú ṣíṣe ìgbédìde àti ṣíṣe ìfidìmúlẹ̀ àwọn ìwà tó dára tó sì tún yanyọ. TS náàni afisí inú “àwọn ìlera tókùdíẹ́káàtó” àti wípé ìtumò rẹ̀ ni gbogbogbò ni lábẹ́ èyí tí àwọn akẹ́kọ̀ọ́ tóní TS ní a ko s'ábẹ́ IEP. Eléyìí ní àwọn ọ̀rọ̀ tí a dìmú látí U.S.Ilé iṣẹ́ ilé ẹ̀kọ́ ní wọ́n woo àwọn ìtumò lòdì sí òtítọ àìléra Tourette Syndrome àti àwọn ìdí tí afifi TS sínú IDEA:

> *“..., àwa kò gbàgbó wípé aṣi àìléra Tourette Syndrome túnmọ̀ láti jẹ ìwà tàbí ipò ìmọ̀lára èèyàn, ṣùgbọ́n tójẹ́ ipò ọpọlọ èèyàn. Nígbànáà, tí ó bá jẹ́bẹ̀, fífi àìléra Tourette Syndrome kún ìtumò àwon ìlera tókùdíẹ́káàtó míràn leè rán ni lọ́wọ́ láti lè ṣàtúnṣe àṣìtúnmọ̀ tí àìléra Tourette Syndrome gẹ́gẹ́bí àisedéédé ìwà tàbí ìdarí àti láti ṣénà mọ́ àṣìtúnmọ̀ oun ti wọ́n ní lò.”*
>
> ***Àyípadà:** Ati fi àìléra Tourette Syndrome ṣí ara àwọn àpẹẹrẹ tàbí àríkọ́gbọ́n tí ìṣòro àìsàn tó lágbára nínú §300.8(c)(9)(i).*

Àwọn Iṣẹ́ ṣíṣe ẹ̀kọ́ tó péye, àwọn àyẹ̀wò àti àwọn agbára pẹ̀lú àwọn ìwò ṣe oun ti akẹ́kòó nílò jùlọ ní àwọn ìpìlẹ̀ fún èyíì ètò IEP àti ètò 504 kan. ***Èyí ètò IEP tàbí 504 ní a gbọ́dọ̀ fí àwọn àfojúsùn tí ó jẹmọ́ àdínkù tîìkì.*** Àwọn ètò yìí leè ní àtìlẹ́yìn láti ọ̀dọ̀ àwọn òṣìṣẹ́ ilé ìwé àti ilé ìgbé àti àwọn àtúnṣe tí a fi sun sí pípèsè àyíká tí ó leè mú àdínkù bá àníyàn àti àmì gbogbogbò. Ìtàkùn àgbáyé nì ló pèsè àwọn olùkọ́ni pẹ̀lú àlàyé àti ohun èlò tó kún rẹ́rẹ́ fún àtìlẹ́yìn àwọn ọmọ ilé ìwé tóní TS.



7__ToolKit12pagerEducatorFinal2020_YO.indd 3 6/9/2022 3:07:42 p. m.

## GBÍGBÉ ÈTÒ ÀTÌLẸ́YÌN SÓKÈ

Kí átó gbé ètò àtìlẹ́yìn tó múná dóko sílẹ̀, àwọn nkànkan tó ṣe pàtàkì kàn wà tí a gbọ́dọ̀ fi akàn.

**Wà ní ìmúrasílẹ̀:** Sí gbígbé ètò kàn kalẹ̀, àjọ tourette ló da lábàá wípé àwon ẹgbẹ́ ètò ẹ̀kọ́*gbọ́dọ̀ kà níní òye àwọn àmì ìwà nínú àìléra Tourette Syndrome: TS ju àwọn àìsedéédé tîîkì.* Àtẹ̀jáde yìí pèsè àlàyé ní ránpẹ́ lórí iye àwọn ìṣòro tó jẹmọ́, tó sì tún wọ́pọ̀ fún àwọn ọmọ ilé ìwé tóní TS. Àtẹ̀jáde TAA yìí, *àwọn ìwé ìtọ̀nà titi olùkọ́ni fún gbígbé àwọn ètò fún àwọn ọmọ ilé ìwé tóní àìléra Tourette Syndrome*, ó sì tún jẹ́ ohun àlùmọ́nì tó se kókó fún ìlò nígbàtí ìpàdé ètò bá nlọ lọ́wọ́ lọ́wọ́. Àwọn àtẹ̀jáde méjèèjì ní ó wà níkàlẹ̀ lórí itakun àgbáyé ní tí àjọ TAA.

**Fí àwọn ọmọ ilé ìwé kún:** Àwọn akẹ́kọ̀ọ́ yìí ní a gbọ́dọ̀ fi sínú ètò yìí gẹ́gẹ́ bí a sẹ́ n ṣe ìpàdé ètò lẹ́sẹ̀kẹsẹ̀. Tí àwọn akẹ́kọ̀ọ́ kò bá rí àtìlẹ́yìn gẹ́gẹ́ bí ìrànlọ́wọ́, irúfẹ́ ani bẹ̀ ni kòní lo wọ́n, tó sì mú kí ètò wọn já sí asán. Àwọn akẹ́kọ̀ọ́ ní ó gbọ́dọ̀ ní ìtẹ́ríba àti wípé kí wọ́n fi ara wọn jì fún àwọn ètò tí yóò mú ìdàgbàsókè bá wọn.

## ÌWÚLÒ ÌBÁRAẸNISỌ̀RỌ̀

Ìbáraẹnisọ̀rọ̀ jẹ́ kọ́kọ́rọ́ fún àwọn ọ̀pọ̀lọpọ̀ ìdí. Ìbáraẹnisọ̀rọ̀ àti àfinútán ní yóò ran àwọn ọgbọ́n àti ìmọ̀ tó múná dóko, gẹ́gẹ́ bí yóò sì tún ṣe kó ipa pàtàkì ní agbègbè ìgbẹ̀kọ́ àwọn ọmọ ilé ìwé. Bíbá àwọn mọ̀lẹ́bí sọ̀rọ̀ ṣe kókó fún ìdàgbàsókè àwọn àjọṣepọ̀ tóní ìbáṣepọ̀ gbogbogbò tí kò wọ́n ṣe kókó sí àṣeyọrí tàbí àseyege àwọn ọmọ ilé ìwé tóní àmì TS.

Ìbáraẹnisọ̀rọ̀ láàrin àwọn ọmọ ẹgbẹ́ nípa ìmùnádóko ètò àtìlẹ́yìn ni ó ṣe kókó. Èyíkéyìí àwọn ìdí tí ó bá lè fa kí àwọn ọmọ ilé ìwé náà di pínpín láàrin àwọn ọmọ ẹgbẹ́, àtúnṣe sí ètò yìí gbọ́dọ̀ di mímú sẹ nígbà tó bá lílò àtúnṣe náà. Àpẹẹrẹ àwọn ìdí tó sàkóbá fún àwọn ọmọ ilé ìwé náà ni àfikún sí àwọn àmì ni rírí ní ààgọ́ ara, wàhálà, àyípadà nínú iṣẹ́ ojoojúmọ́ tàbí àwọn olùpèsè àti àyípadà nínú lílo oògùn. Ó máa n ran ẹgbẹ́ lọ́wọ́ là sọfún wọn nípa àwọn àyípadà yìí ní pàtó, àti àwọn àyípadà sí búburú tàbí dáadáa ní gbogbogbò. Àwọn ẹgbẹ́ ní ó gbọ́dọ̀ ridájú wípé àwọn dáa àwọn ìmọ̀ tó wúlò jọjọ mọ̀, tí ó lè ràn àwọn ọmọ ilé ìwé lọ́wọ́, gẹ́gẹ́ bí ọmọ ilé ìwé kọ̀ọ̀kan ṣẹṣe pàtàkì, tí o sì lè jẹ alábàápín láti ọ̀dọ̀ àwọn ìmọ̀ tuntun tí afi lé dá nkàn míràn sílẹ̀. Àwọn ọmọ ẹgbẹ́ gbọ́dọ̀ ṣọ́ àti pín ìmọ̀ tí ó leè ranni lọ́wọ́ lò tí kò sí múná dóko láti rí dájú pé àwọn yìí kò rú àníyàn tàbí àwọn àmì yókù sókù.

Ní àfikún, àwọn ọmọ ẹgbẹ́ gbọ́dọ̀ bá àwọn ọmọ ilé ìwé sọ̀rọ̀ nípa oun tí ọmọ náà ní gbàgbọ́ pé o lè jẹ ìrànlọ́wọ́. F'etí sílẹ̀ dáadáa sí èrò ọkàn ẹni náà torí ìwòye àwọn akẹ́kọ̀ọ́ náà máa n wúlò gán nígbà tí a bá n ṣàtúnṣe tàbí gbé ìmọ̀ sókè.

## OJÚṢE ÀWỌN OLÙKỌ

Àwọn olùkọ́ kó ipa tó ṣe pàtàkì nínú ayé àwọn ọmọ ilé ìwé. Wọ́n máa sọ bí ìyárá ìgbẹ̀kọ̀ ṣe. Máa rí, wọn máa ṣàtìlẹ́yìn fún ìdàgbàsókè, ọgbọ́n àti agbára, àti àwọn aláwòkọ́ṣe fún àwọn akẹ́kọ̀ọ́. Àwọn olùkọ́ máa n sọ ìyàtọ̀ lá àrin ọmọ ilé ìwé tóní ìrírí TS pẹ̀lú àyíká tó ṣàtìlẹ́yìn fún tàbí eléyìí tí óní wàhálà tí kòsí dára tó. Àjọṣepọ̀ tó dán mánrán láàrin olùkọ́ àti ọmọ ilé ìwé ní yóò sọ nípa àṣeyọrí tàbí ìkùnà ọmọ ilé ìwé náà. Bí ọ tí lẹ̀ jẹ́ wípé gbogbo àwọn ọmọ ilé ìwé àti ọ̀rọ̀ àmì TS ní ó jẹ́ ọ̀rọ̀ kàn gbógì, èyí ni àwọn àbá tó jẹ́ tí gbogbogbò tí ó lè ran àwọn olùkọ lọ́wọ́ nínú síṣàtìlẹ́yìn fún àwọn ọmọ ilé ìwé láti ní àṣeyọrí nínú ètò ẹ̀kọ́ àti láwùjọ:

- Dá tîîkì mọ̀ gẹ́gẹ́bí àwọn ìrìn kiri ti kò wuni àti àwọn ìró tó jẹ wípé àwọn ìdí tó ṣọmọ́ ọpọlọ lófàá. Àìsedéédé tîîkì leè dáa, ó sì leè mú dáa ní ọ̀nà tó pọ̀ àti wípé òun leè kúrò lọ́dọ̀ láàrin wa láàrin rò tẹ̀lẹ̀. Ní gbogbo awọn àpẹẹrẹ, àwọn ọmọ ilé ìwé tóní TS lílò láti pa àìsedéédé tîîkì mọ́lẹ̀ láti leè yẹra fún ìbáraẹnisọ̀rọ̀ tó lòdì láti ọ̀dọ̀ ẹlòmíràn. Bí ọ tí jépé àìsedéédé tic leè jẹ́ nkàn àmọ̀ọ̀mọ̀ọ̀ ṣe'ni tí àkóso rè sí wà lọ́wọ́ ọmọ ilé ìwé náà, eléyìí ní kò jẹ́ òtítọ̀.
- Dín wàhálà àti àníyàn ku Wàhálà ní ṣíṣe má fẹẹ àwọn àmì tic loju Ìmọ̀ tó múná dóko tí à n ló láti mú àdínkù àwọn àmì náà ni láti ṣe àkíyèsí ìṣẹ̀lẹ̀ tàbí àwọn ìdí tó máa fi àfikún bá wàhálà àti tó máa n jẹ́kí ọ̀rọ̀ àwọn ilé ìgbé wá sí ìmúṣ àti àwọn àtúnṣe tàbí àwọn ètò ẹ̀kọ́ tó yàtọ̀ gédégédé.
- Dá àwọn àlébù ìmọ̀ tí o lè fà àfikún bá wàhálà ni ṣíṣe tàbí àwọn àmì, kí o sì dá àwọn ọ̀nà ìmọ̀ àti àtìlẹ́yìn láti le kojú àwọn àlébù yìí.
- Fí ojúdi àwọn àmì. Eléyìí ní ó ṣàfihàn ìtẹ́wọ́gbà àti wípé óún ìṣerẹ́gí tàbí ìṣedéédé wà fún TS. Wíwo àwòṣe ìtẹ́wọ́gbà leè fa àdínkù bá èyí ìpanilára tàbí wàhálà tí ó sì fi ààyè gba àwọn ọmọ ilé ìwé tóní TS láti kọjú mọ́ ètò ẹ̀kọ́ wọn dáadáa Dípò ju ki won ní ìbìnújẹ́ lórí àìsedéédé tîîkì.
- Mọ̀ wípé ìṣòro kíkọ ìwé náà wà lára àwọn ìṣòro ilé ìwé tó wọ́pọ̀ fún ọmọ ilé ìwé tó bá ní TS. Àwọn àkómọ́ra náà lè jẹ́ ìmọ̀ bí a tí nlo ẹ̀rọ ayélujára, tabulẹẹti ìgbàlódé, gègé ìgbàlódé, tàbí gègé àtijọ́ kàn.
- Ṣọ́ra fún àwọn ipò tàbí ìṣẹ̀lẹ̀ onídéédé, bí àwọn OCD tàbí ADHD, eléyìí tó wọ́pọ̀ láàrin àwọn ọmọ ilé ìwé tóní àmì TS. Àwọn ìwà ipò yìí ni o má n dígbà ní ìṣòro tí wọ́n sì le láti sètọ́jú ju àwọn àìsedéédé t fúnra wọn lọ.
- Jẹ́ Olùdásílẹ̀ pẹ̀lú àwọn ìlọ̀wọ́sí rẹ. Kíkọ́ àwọn ìmọ̀ ìgbésí ayé àti pípèsè àti, àwọn ilé ìgbé àti àwọn àtúnṣe ní en ṣe kókó ju gbígbé kẹ̀lẹ́ ìjìyà lọ



7__ToolKit12pagerEducatorFinal2020_YO.indd 4 6/9/2022 3:07:42 p. m.

- Fi àwọn ọmọ ilé ìwé náà eléyìí tó ní TS sínú àwọn ìmọ̀ àti ètò ìdàgbàsókè fún ìtọ́jú àwọn àmì tí o lè tàbí tí kò sé F'ojú fò.
- Ṣe ìgbé l'árugẹ ìbáraẹnisọ̀rọ̀ pẹ̀lú àwọn òbí tàbí aláànúú. Rí dájú láti pín àṣeyọrí àwọn ọmọ ilé ìwé yìí àti agbára wọ́n tí kì sí ṣẹ àwọn kùdìẹ̀kudiẹ wọn.
- Rí dájú wípé àwọn arọ́pò olùkọ mọ̀ nípa àwọn àmì àti àtìlẹ́yìn tí àwọn akẹ́kọ̀ọ́ náà.
- Ìlò àwọn ohun àlùmọ́nì tí TAA, bí *ìwé olùtọ̀nà fún àwọn olùkọ́ fún ètò ìdàgbàsókè fún àwọn ọmọ ilé ìwé tóní àìlera Tourette Syndrome*, láti ṣe ìrànwọ́ pẹ̀lú àtìlẹ́yìn ìdàgbàsókè àti ìmọ̀.

## ÒṢÌṢẸ́ ALÁTÌLẸ́YÌN ÈTÒ Ẹ̀KỌ́

Àwọn òṣìṣẹ́ alátìlẹ́yìn ètò ẹ̀kọ́ ní wọ́n jẹ́ ọmọ ẹgbẹ́ kàn gbógì ti àjọ ilé ìwé àti wípé wọ́n ṣe kókó sí àṣeyọrí àwọn ọmọ ilé ìwé náà. Wọ́n máa n ṣe àwọn oríṣiríṣi iṣẹ́ eléyìí tó o máa pà ìgbésí ayé àwọn akẹ́kọ̀ọ́ náà lára ní ọ̀nà tó gbà dáa, ṣe àbójútó àwọn àyíká fún ẹ̀kọ́ tó dáa àti àtìlẹ́yìn fún ẹ̀kọ́ tó yè Kooro. Àwọn alátìlẹ́yìn ètò ẹ̀kọ́ ní wọ́n wà ní ipò tó ṣe kókó láti ní òye àti láti ṣe ìrànwọ́ fún ọmọdé tóní àmì TS àti àwọn àìsedéédé tîkì. Gẹ́gẹ́bí ọmọ ẹgbẹ́ alájọlọ̀ṣiṣẹ́pọ̀ tí ilé ìwé, Wọ́n leè ṣe ìrànwọ́ nínú rírí dájú wípé àwọn ètò ilé ìgbé tó dára àti àwọn àtúnṣe nípasẹ̀ àwọn oun ìtọ̀nà àti ìrànwọ́ tí a piyamọ lọ́tọ̀ fún wà ní kálẹ̀. Ní ìsàlẹ̀ ní àwọn àbá fún àwọn oníruurú ìrànwọ́ tí alè pèsè sílẹ̀, gẹ́gẹ́bí ipa kọ̀ọ̀kan pàtàkì tí à piyamọ rẹ̀ fún

## IPA Ọ̀GÁ ILÉ ÌWÉ TÀBÍ IPA TI ALÁBÒJÚTÓ

Àwọn Ọ̀gá ilé-ẹ̀kọ́ Àti àwọn alábòjútó ní ó máa n dígbà lọ́wọ́ sí nígbà tí ipò ìbáwí kò bá níyanjú. Ọ́ṣe kókó kí àwọn alábòjútó ní òye nípa TS láti leè rí dájú wípé àwọn ọmọ ilé ìwé kò rí èsì tí kò dára tó fún àwọn àmì TS. Ọ̀gá ilé ìwé tàbí àwọn alábòjútó leè ran àwọn ọmọ ilé ìwé tóní TS lọ́wọ́ ní àwọn ọ̀nà yìí:

- Rí dájú wípé olùbádòwọ̀pọ̀ tí wọ́n lọ́wọ́ pẹ̀lú ètò àti ìdàgbàsókè àwọn ọmọ ilé ìwé láwùjọ ní ìdánilékòó t'inú ètò tó jẹmọ́ TS àti àwọn àìsedéédé míràn tó jọmọ́ọ.
- Tí àwọn òṣìṣẹ́ lẹ́yìn nínú mímọ wípé kòsí ọ̀ràn TS méjì kò jọ ara wọn. TS yóò ṣe àfihàn ararẹ̀ẹ̀ ní orísirísi ònà tó yàtọ̀ pẹ̀lú Olúkálùkù àti nítorí náà ìdásílẹ̀, ìlọ́wọ́sí rere ṣìṣe jẹ́ pàtàkì.
- Ṣe àtìlẹ́yìn àwọn akẹ́kọ̀ọ́ tóní TS àti wípé kí o rí dájú wípé àwọn òṣìṣẹ́ fí tó àwọn òbí tàbí alágbàtọ́ létí nípa bí TS ṣe n ṣe ìpalára lórí iṣẹ́ àwọn ọmọ ilé ìwé tàbí bí wọn ṣele ṣe nkan sí ní ilé ìwé.
- Ṣe ìdánimọ̀ pé TS ní nkàn ṣe pẹ̀lú ọ̀pọ̀lọpọ̀ àwọn ipò bíi: OCH,A DHD, àìsedéédé ìṣiṣẹ́ ọpọlọ, àwọn àlébù ìbáraẹnisọ̀rọ̀ láwùjọ, ìbìnújẹ́, àìsedéédé ìwà, ìṣòro ìkòwé, àníyàn ṣíṣe, ìkọlù Ìrunú, orí fífọ́, ìkọlù àníyàn, àìgbọràn dáadáa àti bẹ̀ẹ̀bẹ̀ẹ̀ lọ. Ìmọ lori tó jinlẹ̀ àti òye àwọn ìṣòro yìí ní yóò ràn àwọn alábòjútó láti ní ìbáṣepọ̀ àti láti ṣiṣẹ́ pẹ̀lú àwọn ọmọ ilé ìwé tóní TS.

## IPA OLÙKỌ́NI TÓ YÀTỌ̀

Àwọn olùkọ́ni tó yàtọ̀ ní wọ́n wà ní ipò tó yàtọ̀ gédégédé láti bá àwọn ohun tí àwọn ọmọ ilé ìwé tóní TS nfẹ́. Àwọn olùkọ́ni tó yàtọ̀ leè sìn gẹ́gẹ́ bí Olùdánilẹ́kọ̀ àti agbọ̀ràndùn Kan nípa fífún àwọn ọmọ ilé ìwé ní àwọn irin iṣẹ́ àti ìtọ́nisọ́nà tí wọn lílò láti ṣe àṣeyọrí. Àwọn olùkọ́ni tó yàtọ̀ máa n yẹ àwọn ọmọ ilé ìwé wò, ṣètò àti ẹ̀kọ́ lẹ́yìn ilé ìwé àti ìtọ́jú IEPs tí wọ́n ṣe péyé tósì tún ṣe kókó sí ǻwọn ohun tí àwọn ọmọ ilé ìwé yóò nílò. Ní ìsàlẹ̀ ní àwọn àbá fún àwọn olùkọ́ni tó yàtọ̀ nígbà tí wọ́n bá n ṣiṣẹ́ pẹ̀lú àwọn ọmọ ilé ìwé tóní TS:

- Mùra sílẹ̀ láti ṣàlàyé fún àwọn alábàáṣiṣẹ́pọ̀ àwọn ọmọ ilé ìwé bí àmì àìṣedéédé ìdàgbàsókè ọpọlọ tó lọ́jú ṣe máa n dígbà jẹ́ kí àwọn ọmọ ilé ìwé ní ìdíwọ́ pẹ̀lú ipá wọn láti dé ibi tòga nínú ètò ẹ̀kọ́ rẹ̀ẹ̀ ní kíkún. Ní àfikún, mọ wípé àwọn àmì yìí ní aleè ṣìtúnmọ̀ gẹ́gẹ́bí àwọn ìwà tó nídìí tí ó lọ́wọ́ sí àwọn ìmọ̀ ìbáraẹnisọ̀rọ̀ l'áwùjọ tó péyé.
- Pèsè ohun àlùmọ́nì láti ran àwọn ìyókù lọ́wọ́ nínú nìnì òye wípé àwọn àmì àti ìwà ti àìṣedéédé tó lọ́jú yìí kìí ṣe àmọ̀mọ̀ṣe.
- Ran àwọn ìyókù lọ́wọ́ nínú ìdàgbàsókè àti rírí àwọn ìlànà tí a piyamọ dájú, àwọn àtúnṣe àti àwọn ilé ìgbé.
- Pinu láti ní ìmọ̀-ẹ̀rọ ìrànlọ́wọ́, gẹ́gẹ́ bí àwọn tîkì àti àwọn àìṣedéédé míràn tó jọ ara wọn máa n dígbà dásí ìkọ̀wé àti ìkàwé.
- Dá àwọn akẹ́kọ̀ọ́ tó leè ní àlébù ìkàwé tó máa n dígbà ṣẹlẹ̀ àti/tàbí wà ní ìwọ̀n ẹ̀bùn ní ọgbọ́n. Ọ́ṣe kókó láti wò kọ́ja àwọn àmì TS kí á sì ṣe àyẹ̀wò tó múnádóko.
- Rí dájú wípé àyíká àti ipò ìdánrawò wà nílẹ̀. Láìbìkítà láti wo wíwá tàbí ìsánsá àwọn ìṣòro ẹ̀kọ́ kíkọ́, àwọn ọmọ ilé ìwé tó n dígbà TS ní wọ́n má nílò àkókò díẹ̀ síi láti ṣe ìgbéléwọ̀n. Ìdánwò ní agbègbè ọ̀tọ̀ọ̀tọ̀ pẹ̀lú àwọn àkókò ètò tí a fẹ̀ lójú leè jẹ́ ilé ìgbé dandan láti fí àjọ IEP tàbí 504 sétò.
- Agbọ̀ràndùn fún àwọn ọmọ ilé ìwé tóní TS. Wọ́n lẹ́tọ̀ọ́ sí ààbò àyíká kàn náà gẹ́gẹ́ bí àwọn ọmọ ilé ìwé yòókù tóní àwọn àlébù. Ní gbogbo, ní a máa yọ wọn kúrò nínú àyíká ètò ẹ̀kọ́ tí gbogbogbò nítorí àìsedéédé tîkì wọn ló máa n jẹ́ ìṣòro fún àwọn míràn. Ọ́ṣe kókó láti yanjú àwọn ìṣòro yìí kí á sì máa ṣe iye àkókò tí àwọn akẹ́kọ̀ọ́ yìí lò ní ìta àwọn ìyárá ìkẹ́kọ̀ọ́ tí gbogbogbò.

## IPA OLÙDÁMỌ̀RÀN ÀTI OLÙKỌ́ ÀWỌN OHUN ÀLÙMỌ́NÌ.

Àwọn olùdámọ̀ràn àti àwọn olùkọ́ ohun àlùmọ́nì ní wọ́n má n dígbà jẹ́ àfikún to lágbára, gẹ́gẹ́ bí wọn ṣe ní anfààní sí ohùn àlùmọ́nì láti ran àwọn olùkọ àti ọmọ ilé ìwé àti akẹ́kọ̀ọ́ láti ní òye En tún leè wúlò gidigan nínú ìrànwọ́ àwọn ọmọ ilé ìwé tón ṣe àgbédìde àwọn ìmọ̀ oníkálukú fún ìtọ́jú àwọn àmì tí ó ṣòro. Olùdámọ̀ràn àti àwọn olùkọ́ ohun àlùmọ́nì leè:

- Ràn àwọn ọmọ ilé ìwé láti ṣe ìtọ́jú isẹ́ tó pọ̀ fún wọn láti leè ṣénà mọ́ àwọn àpọ̀jù ìmọ̀lára.
- Ràn àwọn ọmọ ilé ìwé lọ́wọ́ láti leè ṣàgbékalẹ̀ ìmọ̀ ìgbésí ayé fún àbójútó àwọn ìṣòro bíi ètò àti ṣíṣó àkókò lò.
- Pèsè ibi kékeré kan láti ṣe àwọn ìdánrawò ránpẹ́, àwọn ìbéèrè àti ìdáhùn àti àwọn iṣẹ́ àgbéyẹ̀wò míràn.
- Ṣiṣẹ́ pẹ̀lú àwọn olùkọ láti pèsè àwọn àtìlẹ́yìn tó péye, àwọn àtúnṣe àti àwọn ilé gbígbé.
- Ràn àwọn alábàáṣiṣẹ́ pọ̀ lọ́wọ́ nínú mímú àkókò àti ìgbà ìṣe àwọn iṣẹ́ àmúrelé náà lọ́pùnpúndùn, eléyìí tó lè mú àdínkù bá àníyàn ní ṣíṣe.
- Ṣè ìwádìí àwọn ìmọ̀, sì tún ṣe àbẹ̀wò sí ìtàkùn àgbáyé niì fún àlàyé tí yóó ṣe ìrànwọ́ fún gbogbo àwọn alábàáṣiṣẹ́ pọ̀ àti ọmọ ilé ìwé.

## IPA AFÌṢEMÒRÒNÚ NÍNÚ ILÉ ÌWÉ

Láti ti rí anfààní àwọn ọmọ ilé ìwé náà dájú, àwọn afiṣemọ̀rònú tí ilé ìwé ní wọn ó ṣe àyẹ̀wò àwọn agbára àti agbègbè tí ọmọ ilé ìwé kàn tí kúdíẹ̀káàtó nítorí kí sàgbédìde àwọn ètò oníkálukú. Àwọn afiṣemọ̀rònú ilé ìwé ní àwọn òṣìṣẹ́ àti àwọn òbí ilé ìwé máa n wò gẹ́gẹ́bí akọ́ṣẹ́mọṣẹ́ tí yóò pèsè ìmọ̀ràn ìtọ́nisọ́nà gbogbogbò lórí pípèsè àtìlẹ́yìn tótọ́ fún àwọn ọmọ ilé ìwé tóní TS. Ó jẹ́ bùkátà tó ṣe gbógì tàbí ṣe pàtàkì láti ràn àwọn afiṣemọ̀rònú ilé ìwé lọ́wọ́ láti ṣe:

- Jẹ́ oníkálukú náà ní ibi àwọn ìpàdé tó dá àwọn ọmọ ilé ìwé tóní èsì ìdánwò ránpẹ́ tóga àti èyí tókùdíẹ̀káàtó ni won nílò láti rí ògbùfọ̀ fún wọn eléyìí tí yóò jẹ̀ẹ́ kó di mímọ̀ wípé wọ́n ní agbára eléyìí tó ju ìdajì lọ, ṣùgbọ́n gẹ́gẹ́bí àwọn ènìyàn tó ní agbára tí kò ṣèé kojúwò eléyìí tí a tí ipasẹ̀ agbègbè tókùdíẹ̀káàtó eléyìí tí a gbọ́dọ̀ pèsè àtìlẹ́yìn rẹ̀.
- Rán àwọn alábàáṣiṣẹ́pọ̀ ọmọ ilé ìwé náà létí láti máa kọ àwọn ọ̀rọ̀ àfojúsùn ti ọlọ́dọọdún tàbí àmì àṣeparí tó wà lára àdínkù ní kò dára tó.
- Ní òye ọ̀pọ̀lọpọ̀ àwọn àìṣedéédé tó jọ ara wọn tó tùn wọ́pọ̀ àti bí àwọn àìṣedéédé yìí tí ní ipá lórí ètò ẹ̀kọ́ àti ìdàgbàsókè l'áwùjọ.
- Pèsè àlàyé fún àwọn olùkọ àti àwọn òṣìṣẹ́ alátìlẹ́yìn lórí bí àìṣedéédé tîìkì àti àmì bií ìgbìyànjú ọpọlọ, èyí tón yípadà tó sì tún lọ sókè sílẹ̀.
- Ṣàlàyé bí aṣe ṣe àṣìtùmọ̀ àmì àìnídìwọ̀ọ́ tó ṣe pàtàkì tóga jùlọ síbẹ̀síbẹ̀ tó tún ṣe kókó gidigan, eléyìí tí a mán n ṣe àṣìtúnmọ̀ rẹ̀ sí àwọn ìwà “búrúkú” tí a mọ̀ọ́mọ̀ ṣe.
- Dá àwọn ìfarapẹ́ra tó wà láàrin àìlègbọ́ràn dáadáa àti TS láti ṣe àyẹ̀wò ìdí pàtàkì fún àwọn ìpènijà ní fínífíní àti láti pèsè àwọn àtìlẹ́yìn tó péye.
- Ní ànfààní láti leè ṣàlàyé fún àwọn òṣìṣẹ́ ilé ìwé àti àwọn òbí wípé àwọn àmì yìí ní wọ́n dígbà pọ̀si nígbà gbogbo ní ilé, eléyìí tí kìí ṣe àbájáde ìtọ́ọmọ ní “ọ̀nà tí kòda” titi àwọn òbí.
- Dá àwọn ìwòyé TS tón ṣini lọ́nà tó sì tùn wọ́pọ̀ mọ̀ọ̀ (àpẹẹrẹ ọmọ ilé ìwé ní wọ́n jẹ́ àwọn tó máa n wá àkíyèsi àti tí wọ́n sì máa n mọ̀ọ́mọ̀ ba nkàn jẹ́), gẹ́gẹ́ bí àwọn ìwòyé yìí kò ranni lọ́wọ́ tàbí jẹ́ pípé.
- Wà ní ìmúrasílẹ̀ láti ṣè ìwádìí ìtàkùn àgbáyé ti TAA àti wípé kí o kàn sí abala àlàyé àti ìfiṣọwọ́sí àti Àwọn Olùgbaninímọ̀ràn ètò ẹ̀kọ́ fu]n àfikún àlàyé Ṣọwọ́ sí *iwé-iṣẹ́ TAA fún ìdarí àgbéyẹ̀wò ìwà tó n ṣiṣẹ́ àti kíkọ ètò ìdásí tàbí àbẹ̀wò ìwà tóda fún ọmọ ilé ìwé tóní àìléra Tourette Syndrome*.



7__ToolKit12pagerEducatorFinal2020_YO.indd 6 6/9/2022 3:07:42 p. m.

## IPA OLÙDÁMỌ̀RÀN ILÉ ÌWÉ

Àwọn olùdámọ̀ràn ní àwọn ọmọ ilé ìwé máa n dígbà rí gẹ́gẹ́bí ẹnití ó rọrùn láti básọ oun tí óún dùn wọ́n lọ́kàn àti ní ìgbà ìṣòró wọn. Àwọn olùdámọ̀ràn ní wọ́n le pèsè àtìlẹ́yìn fún àwọn ọmọ ilé ìwé tóní TS ní àwọn ònà yìí:

- Ṣíṣe aáyan àníyàn àti ìṣòro ìmọ̀ àwùjọ nípasẹ̀ ìmọ̀ràn oníkúlùkù àti/tàbí ìmọ̀ràn ẹgbẹ́ kékeré.
- Pèsè ètò ìgbafẹ́ tàbí ìlànà ètò àìní wàhálà.
- Ṣe agbọ̀ràdùn fún àwọn ọmọ ilé ìwé tí ọmọ ilé ìwé náà yóò bàá ṣe alábàpín láti ara ètò 504 tàbi IEP kan.
- Ẹ sọ̀rọ̀ àwọn ìpènijà bíi ìpanilára, àwọn olùkọ́ pàtàkì tàbí àwọn ìyàrá ìkẹ́kọ̀ọ́ pàtàkì, ilé oúnjẹ, tàbí àwọn ẹ̀ka.
- Piyamọ ibì kan tó láábòò láti dín àníyàn kù àti láti ṣe ìtúsílẹ̀ tîìkì, tí ó bá jẹ́ dandan.
- Ran àwọn òṣìṣẹ́ àti àwọn ọmọ ìyàrá ìkẹ́kọ̀ọ́ nínú níní òye àwọn àmì tó lee gidigan.
- Jẹ́ ẹni tí àwọn òbí lee f'ọkàn tán.
- Pèsè àlàyé àti wípé fa ojú àwọn ohun àlùmọ́nì TAA mọ́ra, eléyìí tí àwọn òbí àti ara ilé ìwé ní ànfààní sí.

## IPA ÀWỌN DÓKÍTÀ TÓN RÍSÍ ÌLERA LẸ́NU IṢẸ́

Àwọn dókítà tón rísí ìlera lẹ́nu iṣẹ́ jẹ́ àwọn ọmọ ẹgbẹ́ kan gbògî tí wọ́n leè ṣe íránwọ́ nínú bíbá àwọn ohun tí àwọn ọmọ ilé ìwé tóní TS nílò. Àwọn dókítà tón rísí ìlera lẹ́nu iṣẹ́ leè ranni lọ́wọ́ láti dín ipa TS kùn àti àwọn àìṣedéédé mìíràn tó jọ ara wọn nípa ṣíṣe aáyan ìṣòro eléyìí tókó alábòójútó tón ṣíṣẹ́, ìṣẹ́po ọpọlọ àti ìkọ̀wé. Láàrin ilé ìwé, àwọn dókítà tón rísí ìlera lẹ́nu iṣẹ́ leè:

- Mọ̀ wípé ọ̀pọ̀lọpọ̀ àwọn ọmọ ilé ìwé tóní TS ní wọ́n ní àléèbu ìkọ̀wé sílẹ̀ àti wípé wọn á nílò láti ní ànfààní sí ẹ̀ro ayélujára fún àwọn iṣẹ́ àmúrelé kíkọ wọn, ẹ̀dà àwọn ìwé tí a kọ tàbí ìlò ìkọ́wé ìgbàlódé fún ìkọsẹ́ sílẹ̀.
- Sàyẹ̀wò àwọn ìmọ̀ tó n ṣiṣẹ́ nínú ọpọlọ àti wípé kí o ṣàgbékalẹ̀ ètò kan tó yóò gba ọmọ ilé ìwé láàyè láti ní òye, ṣaáyan kí o sì ṣe ìtẹ́wọ́gbà ìṣòro ọpọlọ súlẹ̀ ọjọ́ náà.
- Ran àwọn ìyókù le nínú níní òye wípé ọ̀pọ̀lọpọ̀ àwọn ọmọ ilé ìwé tóní TS ni wọ́n ní àwọn ìṣòro ọpọlọ, eléyìí tó le farahàn láti jẹ́ àwọn ìwà olùtakò.
- Pèsè àwọn ohun èlò ìmúdọ́gba, bíi àwọn ìjókòó pàtàkì tàbí ìdì ìkọ̀we mú, láti ṣe ìrànwọ́ fún ìfisí ọpọlọ àti/tàbí ipò tó dára jù lọ fún àwọn iṣẹ́ ṣíṣe tí à bèèrè yìí.
- Ṣèdarí àwọn àyẹ̀wò ìmọ̀ ẹ̀rọ ìrànwọ́. Àwọn ẹ̀rọ tó wà nílẹ̀ náàni òùnkàwé àti àwọn ètò ìdarí ohùn síi ìwé kíkọ.
- Ṣisẹ́ olú àwọn ọmọ ilé ìwé láti ṣàgbékalẹ̀ àwọn ìmọ̀ iṣẹ́ alábòjútó tí a nílò láti ṣàkóso àkókò, àwọn iṣẹ́ àti àwọn ohun ìní, gẹ́gẹ́bí àwọn eléyìí tiṣe wọ́pọ̀ ṣùgbọ́n síbèsíbẹ̀ ó sì tún jẹ́ ìpènijà pàtàkì tí a kò dámọ̀ fún àwọn ọmọ ilé ìwé tóní TS.
- Ṣe ìdánimọ̀ pé àwọn akẹ́kọ̀ọ́ tóní TS ní wọ́n máa n ṣe dáadáa ní gbà gbogbo lórí àwọn ìwọ̀n ìgbéléwọ̀n tó péye nígbà tó jẹ́ wípé wọ́n darí wọn ni, wọ́n ṣe ìpadé àwọn iṣẹ́ ṣíṣe tó ti parí ní àyíká tí a ṣe ìṣàkóso rẹ̀.
- Se Ìfọ̀rọ̀wánilẹ́nuwò fún àwọn òbí nípa ipá ọmọ ilé ìwé náà láti múra fún ilé ìwé, ṣẹ̀tò àti parí àwọn iṣẹ́ àmúrulé rẹ̀ àti mímọ̀ ìwúlò fún-un láti ṣaáyan àwọn ìmọ̀ tí ìmọ̀lára-àwújọ, ipò iṣẹ́ ṣíṣe àti àwọn Wàhálà àìrórunsún.



- Ṣe àyẹwò fíníífíní lórí gbogbo agbègbè ní àyíká ìkọ láti mọ̀ nípa agbára ọmọ ilé ìwé náà láti kópa, ṣàgbéyẹ̀wò àlàyé nínú ọpọlọ àti iṣẹ́ ṣíṣe ní àwọn ọjọ́ orí tó bá ipò náà mu
- Mọ̀ wípé bí àwọn ọmọ ilé ìwé ṣe n lọ̀ṣi ààrín àti ilé ìwé gíga, ìmọ̀ràn ìlera lẹ́nu iṣẹ́ gbọ́dọ̀ dá lórí ṣí ṣàgbékalẹ̀ àwọn ìmọ̀ àti ọnà ìmọ̀ èro fún ayéràyé lẹ́yìn ilé ìwé.



7__ToolKit12pagerEducatorFinal2020_YO.indd 7 6/9/2022 3:07:42 p. m.

## IPA ONÍMỌ̀ NÍ PÀ ỌRỌ̀-ÈDÈ

Onímọ̀ nípa òrò-èdè lè ṣe ràn wọ́ fún àwọn ọmọ ilé ìwé tóní TS pẹ̀lú oun tó ju ọ̀rọ̀ sísọ lọ tàbí ìkólòlò. Ó jẹ́ dandan wípé SLP ní òye bí TS ṣe n ṣiṣẹ́ àti wípé kí wọ́n máa àwọn àtìlẹ́yìn rere àti ọgbọ́n láti dín àwọn àmì náà kù. Èyí yóò rí dájú wípé ìdánwò ní àfihàn ipá ọmọ ilé ìwé, àti wípé àwon èsì ní a kò lọ́wọ́ sí ní torí àwọn àmì tí a sì túnmọ̀ tàbí ṣìṣàkóso. Onímọ̀ nípa òrò-èdè gbọ́dọ̀:



- Ní ìmọ̀ nípa TS àti wípé ko ní òye nípa bí ó ṣe yàtọ̀ sí ipò àárùn ọpọlọ míràn (àpẹẹrẹ àìlègbọ́nràn) kí ìgbéléwọ̀n tí ó yẹ àti ìtọjú tó péye bá lè wàá sí ìmúṣẹ.
- Mo wípé ẹ̀kọ́ èdè tó dá lé lórí àwọn ìpènijà ní ó wo, eléyìí tí ó le lọ́wọ́ sí ipá látí le báraenisọ̀rọ̀ dáadáa, láti ní òye nkàn tí wọ́n sọ, ṣe àkójọ àwọn ìfiránṣẹ́, àti/tàbí àwọn agbègbè ìbáraẹnisọ̀rọ̀ míràn.
- Ní ànfààní ni ṣe àyẹ̀wò àti láti ṣè ìtọ́jú àìṣedéédé ìbáraẹnisọ̀rọ̀ l'áwùjọ(SCD), ìpènijà eléyìí tó wọ́pọ̀ fún àwọn ọmọ ilé tóní TS.
- Lóye wípé àwọn ọmọ ilé ìwé yìí ni wón máa n dígbà bi sínú wàhálà fún "àwọn ìwà wọn" wípé wọ́n mọ wípé kò t'ọ̀nà ṣùgbọ́n ní àkókò náà wọn kò mọ nkàn tó mọ́.
- Ṣe ìrànwọ́ nínú sí ṣàgbékalẹ̀ àwọn ìmúlò fún ṣíṣe àti ìtọ́jú àwọn ọ̀rẹ́, eléyìí tó jẹ́ wípé ìpènijà tó wọ́pọ̀ ní fún àwọn ọmọ ilé ìwé tóní Ts.
- Mọ̀ wípé àwọn ọmọ ilé ìwé tóní TS ní wọ́n máa n dígbà ṣe àyẹ̀wò ọ̀dì gẹ́gẹ́bí àìlègbọ́nràn àti SCD yẹn ní nílò ìwòse nígbàtí á kò àwọn ìbéèrè kíkún fún àìlègbọ́nràn.
- Mọ̀ wípé ìsúnmọ́ imọ̀ ìtọ́jú ìṣèègùn ìbílẹ̀ láwùjọ tí a piyamọ rẹ̀ fún àìlègbọ́nràn ní nígbà gbogbo ni wọn kò kín múná dóko fún àwọn ọmọ ilé ìwé tóní àìléra Tourette Syndrome/SCD Nígbàtí a bá n pinnu àwọn ìmọ̀ tó yẹ, óse kókó láti ṣiṣẹ́ pẹ̀lú àwọn ọmọ ẹgbẹ́ ìyókù tí àwọn alábàáṣiṣẹ́pọ̀ láti mú àwọn agbègbè to nílò ìtọ́jú àti ìdàgbàsókè lọ láti gbé ìmùnádóko, ètò ìtọ́jú ìfiyàjẹni.
- Ní òye bí TS ṣẹlẹ ní ipá lórí ohùn àti ìjagaara láti máa àwọn ìfọwọ́sí tó péye àti/tàbí àwọn ìlọ́wọ́sí.
- Mọ̀ pé àlébù irọ̀rí èdè/alábòjútó iṣẹ́ ní o wọ́pọ̀ pẹ̀lú àwọn ọmọ ilé ìwé tóní TS àti wípé wọ́n kò kín dígbà sọ̀rọ̀ nípa rẹ̀, eléyìí tí óún jású láti lè kọ̀wé àti láti mú ìmọ̀ tàbí ọgbọ́n ìgbésí ayé lò.
- Ràn àwọn ìyókù lọ́wọ́ nínú mímú wípé àwọn ọmọ ilé ìwé tóní TS ní a dá mọ̀ wípé wọ́n ya "ọ̀lẹ" tàbí wọn kò ní "ètò" nítorí pé okùnrin tàbí obìnrin náà ni ó kùnà láti ní ìmọ láti ṣe ìtọ́jú àwọn ìbéèrè pípàrọ̀ àwọn ìyárá ìkẹ́kọ̀ọ́, níní àwọn ohun tí a nílò fún ìyárá ìkẹ́kọ̀ọ́ kọ̀ọ̀kan, ṣíṣe àwọn iṣẹ́ àmúrelé, tàbí mímọ ibi àti bí aó ṣe bẹ̀rẹ̀ iṣẹ́ àmúrelé náà.

## IPA ONÍMỌ̀ NÍPA ÌWÀ

Àwọn onímọ̀ nípa ìwà ní a máa n so fún láti ṣàgbékalẹ̀ àwọn ètò láti ṣe àtìlẹ́yìn fún àwọn ọmọ ilé ìwé tóní TS, ó jẹ́ ohun kan tí o ṣe kókó láti ní ìdánimọ̀ àwọn àmì tí TS àti àwọn àìṣedéédé míràn tó jẹ mọ́ọ. Ní gbà gbogbo àwọn ìwà ní àn f'ojú ète wò tàbí irú oun tí ojẹ́mọ, ṣùgbọ́n tí kò tọ́, àìsedéédé. Àwọn onímọ̀ nípa ìhùwàsí ní a dálé lórí láti pèsè àwọn àlàyé tó ní ṣe nípa àṣìtúnmọ̀ àti àìsedéédé to le. Àwọn eléyìí ní a lè rí mú nípa àwọn ọ̀nà wọ̀nyí:

- Fa àwọn ìṣòro TS àti àwọn àìsedéédé míràn tó jọ ara wọn mọ́ra, nípa ṣíṣe ìwádìí lórí ìtàkùn àgbáyé nì tí TAA.
- Kàn sí abala àlàyé àti ìfiṣọwọ́sí tí TAA, tí wọn o sì darí rẹ sí akọ́ṣẹ́mọṣẹ́ tó yẹ lórí Àwọn Adarí tàbí alábòjútó olúgbanínímọ̀ràn ti ètò ẹ̀kọ́.
- Ṣọwọ́ sí *ìwé-iṣẹ́ TAA fún ìdarí àgbéyẹ̀wò ìwà tó n ṣiṣẹ́ àti kíkọ ètò ìdásí tàbí àbẹ̀wò ìwà tóda fún ọmọ ilé ìwé tóní àìléra Tourette Syndrome*.
- Ní òye isẹ́ ti àwọn ìbájọra àti àwọn ìyàtọ̀ láàrin àìlègbọ́nràn àti TS.



7__ToolKit12pagerEducatorFinal2020_YO.indd 8 6/9/2022 3:07:42 p. m.

- Ṣe ìdánimọ̀ ìmúnádóko tí àwọn ìlọ́wọ́sí rere fún àwọn àmì TS, àti àìlágbára tí ìjìyà àti èrè.
- Wà ní ìmúrasílẹ̀ láti ṣàlàyé àwọn ànfàní kíkọ́ àwọn nípa àwọn ìmọ̀ ìgbésí ayé láti fi ṣe ìrànwọ́ ní nínú ìsàkóso àwọn àmì ìṣòro tó le.
- Pín ìmọ̀ pẹ̀lú àwọn òbí àti olùkọ́ nípa àlàyé àti àtìlẹ́yìn tó wà níkàlẹ̀ láti ọwọ́ TAA.

## IPA OLÙRÀNLỌ́WỌ́ ÀTI ÀWỌN TÍ KÒ TÍ KỌ́ṢẸ́MỌṢẸ́

Àwọn olùrànlọwọ olùkọ́ àti àwọn tí kò tí kọ́ṣẹ́mọ́ṣẹ́ ní wọ́n dígbà ní ìbáraẹnisọ̀rọ̀ eni sí ẹni pẹ̀lú àwọn ọmọ ilé ìwé àti wípé wọ́n lè kó ipá to ṣe kókó tàbí pàtàkì nínú ààbò òye ọmọ ilé ìwé kan. Nípa fífi etí sílẹ̀ fún àwọn ohun awọn ọmọ ilé náà nílò àti ṣíṣe àwọn àtìlẹ́yìn rere, olùrànlọ́wọ́ tàbí ẹnití kòtí not iṣẹ́ dájú kan lè ṣe ìrànlọ́wọ́ àti fí fi ìmọ̀ rere tó múná dóko lélẹ̀ gẹ́gẹ́bí àwọn ètò rere tó wà lára àwọn ìhùwàsí ọmọ ilé ìwé. Àwọn akẹ́kọ̀ọ́ náà ló gbọ́dọ̀ mọ̀ wípé àwọn aláìmọ̀ṣẹ́dájú ní o wà ní ẹ̀gbẹ́ rẹ̀ gẹ́gẹ́ bí olùpèsè àtìlẹ́yìn tó yẹ àti ẹni tí o wà gẹ́gẹ́ bí alábòò tàbí olùfípamọ́, dípò àgbàlagbà kàn tó wà níbè láti má ṣọ́wọ lọ́wọ́lẹ́sẹ̀. Èyí le ṣe ìrànlọ́wọ́ láti mú àdínkù bá wàhálà àwọn ọmọ ilé ìwé àti àwọn àdínkù àmì tîìkì, tó jẹ́ wípé ó yọrí sí àyíká èto ẹ̀kọ́ tó ṣe àṣeyọrí síi dáadáa. Àwọn wọnyí ní àwọn àbá tó ṣe pàtàkì:

- Ní òye àwọn ìmọ̀ tó ti ṣíṣe fún àwọn fún àwọn ọmọ ilé ìwé dáadáa.
- Ṣọ́ra fún oun tó lè ru àníyàn àwọn ọmọ ilé ìwé náà sókè àti àwọn àmì.
- Mọ̀ nígbà tí o yẹ ká fí ààyè tàbí ìgbà àṣírí sílẹ̀ àti ìgbà láti ṣe àtìlẹ́yìn.
- Ṣe ìdánimọ̀, sí gbà wípé ọmọ ilé ìwé náà gbọ́dọ̀ rí ọ gẹ́gẹ́ bí alábòò rẹ̀ àti ẹni tí ó wà kan wọn.
- Ṣe ìdánimọ̀ pàtàkì iṣẹ́ ṣíṣe pẹ̀lú omo ilé ìwé yìí.
- Ní ìtara láti ní àwọn ìjíròrò pẹ̀lú olùkọ́ ọmọ yìí nípa TS.
- Ṣàgbékalẹ̀ ètò kàn nípasẹ̀ èyí tí o lè má bá àwọn olùkọ́ sọ̀rọ̀ nípa àwọn iṣẹ́ ṣíṣe àti àwọn àyíká eléyìí tí ó n mú àfikún àti/tàbí àdínkù bá àwọn àmì.

## IPA NỌ́Ọ̀SÌ ILÉ ÌWÉ

Nọ́ọ̀sìì ilé ìwé ní ó jẹ́ akọ́ṣẹ́mọṣẹ́ tí ó lè pèsè àlàyé ìṣèègùn. Nítorí èyí, àwọn akẹ́kọ̀ọ́ àti òbí náà ni yó yípadà sí ọ̀dọ̀ àwọn nọ́ọ̀sìì fún àtìlẹ́yìn nínú kíkọ́ àwọn òṣìṣẹ́ ilé ìwé nípa àìsedéédé ìdàgbàsókè ọpọlọ tó le yìí. Láti ṣe ìrànwọ́ nínú èyí:



- Pèsè àlàyé nípa TS àti àwọn àìṣedéede tó n wáyé ni gbogbo ìgbà láti ṣe ìrànwọ́ fún àwọn akẹ́kọ̀ọ́ tí a kò tí ṣe àyẹ̀wò fún tàbí àwọn tí àti ṣe àyẹ̀wò fún.
- Bá àwọn òbí tí wọ́n lè tako àyẹ̀wò yìí.
- Pèsè ibi ààbò fún n ọmọ ilé ìwé náà láti sinmi àti láti tú àwọn tîìkì sílẹ̀, gẹ́gẹ́bí ati nílò wọn.
- Ṣe àkíyèsí àwọn òògùn àti ipá lára òògùn náà.
- Pèsè ibi ààyè kan fún ìrẹjú ránpẹ́, eléyìí tí o lè wúlò nítorí àwọn ìpalára òògùn náà.
- Ṣe ìdánilẹ́kọ̀ọ́ fún àwọn òṣìṣẹ́ nípa tîìkì àti àwọn ìṣòro míràn tó jọmọ́ọ.
- Pèsè àlàyé ìṣègùn nígbà àwọn ìpàdé IEP tàbí ètò 504.

## IPA AWAKỌ̀ ÀTI ÀWỌN OLÚNJE

Àwọn awakọ̀ àti àwọn olúnje ní oníkálukú tó n ṣiṣẹ́ ní àyíká láiní ilé tàbí àbójútó, ní gbogbo ìgbà ní àyíká má n jẹ́ àyíká tó lè púpọ̀ fún àwọn ọmọ ilé ìwé tóní TS. Àwọn ọmọ ẹgbẹ́ òṣìṣẹ́ ní wọ́n le kópa tó jọjú nípa ṣíṣe àwọn nkàn wọ̀nyìí:

- Ní òye pàtàkì ìpènijà tí àwọn ọmọ ilé ìwé tóní TS n kojú lójoojúmó.
- Ṣe ìdánimọ̀ pé ọ̀pọ̀lọpọ̀ àwọn ọmọ tóní TS ní àwọn ìṣòro ọpọlọ eléyìí tó lè mú àfikún báa ní àyíká ti ariwo bá pọ sí àti àyíká tó kò ní ètò gẹ́gẹ́bí ilé oúnjẹ àti ọkọ̀ akérò.
- Mọ wípé nígbà tí àwọn àyíká yìí lè jẹ́ àyíká ti ṣòro, àwọn ètò yìí lè ṣe Aṣojú fún ànfààní láti bá ara ẹni sọ̀rọ̀ láwùjọ àti láti gbafẹ́ nìkan.
- Mo wípé àwọn àmì náà ni ó máa n pósí ní òpin ọjọ́ náà.
- Ṣọ́ra fún àwọn ọmọ ilé ìwé tí wọ́n tí ṣe ìpalára fún, eléyìí tí o lè fi kún àwọn tic ọmọ ilé ìwé náà.
- Ṣàgbékalẹ̀ ìbáṣepọ̀ èyí tí àwọn akẹ́kọ̀ọ́ le sọ̀rọ̀ ìṣòro àti ìmọ̀ tàbí ọgbọ́n láláìléwu.
- Jábọ̀ àwọn ìṣòro fún àwọn alákòóso kí wọn tó fẹ̀ lójú.
- Ṣe àkíyèsí àwọn ètò ìmọ̀ tàbí ìhùwàsí àti bí wọ́n ṣe lè ṣèrànwọ́ fún akékòó kan.

## IPA Ọ̀JỌ̀GBỌ́N ILÉ ÌWÉ GÍGA

Àwọn ọ̀jọ̀gbọ́n kọ́lẹ́ẹ́jì ní wọ́n kópa tó làmì laaka nínú àṣeyọrí kọ́lẹ́ẹ̀jì àti wípé wọ́n lọ́wọ́ sí ìdádúró ọmọ ilé ìwé. Àwọn ọ̀jọ̀gbọ́n ní wọ́n máa n ní ìfarakora pẹ̀lú àwọn ọmọ ilé ìwé àti wípé wọ́n lè gbà wọ́n níyànjú àti wípé wọ́n tún lè ṣe àkóso wọ́n láti ọnà jínjìn lórí ànfààní àti oun tí wọn fẹ́. Wọ́n tún lè ní ipá tó lágbára lórí ànfààní ọmọ ilé ìwé láti lè ṣe àṣeyọrí nínú èka iṣẹ́ eléyìí tó mú. Àwọn ọmọ ilé ìwé náà ni wọ́n lè ní ìpalára nípasẹ̀ ìdájọ àwọn alábòjútó ẹ̀ka ilé ìwé wọn lórí ìròrí wọn eléyìí tó jẹ́ wípé àṣìtúnmọ̀ TS ní ó ṣe okùnfà rẹ̀, léyìí tó lè ṣe ìpalára fún ìgbàgbọ́ ọmọ ilé ìwé náà nínú ara rẹ̀. Ó lè ṣe ìrànwọ́ sí:

- Ṣe ìdánimọ̀ ara rẹ fún àwọn ọmọ ilé ìwé yìí, kí ó sì bí wọ́n ọ̀nà tí o leè gbà rànwọ́lọ́wọ́.
- Ṣe ìdánilékọ̀ọ́ fún ara rẹ nípa TS. Níní òye ìpìlẹ̀ nípa TS àti àwọn àìṣedéédé míràn tó jọmọ́ọ leè ṣe ìgbáradì fún ọ nípa àfihàn lórí tic mọto àti tic ohùn nígbà tí a bán ṣíṣe lọ́wọ́ ní ìyárá ìkẹ́kọ̀ọ́.
- Ṣe ìdánimọ̀ àwọn ìrìn kiri àti ìró tí kìí ṣe àtinúwá eléyìí tó lè yípadà láìròtẹ́lẹ̀. Nígbàtí àìsedéédé tic leè dàbí ẹni tí óní ìdí àti bí oun tó wà ní ìkápá ènìyàn náà, eléyìí ní kìí ṣe òtítọ́. Akò gbọ́dọ̀ retí kí àwọn ọmọ ilé ìwé dín àìṣedéédé tîkì wọn kù. Tí àwọn àìsedéédé tîkì bá diní lọ́wọ́ nítòótó, àwọn àsàyàn ẹ̀lẹ́tíróníìkì ní ó yẹ ká mú lò.
- F'ojú fo àwọn àmì tí ó ṣe f'ojú fò. Eléyìí ní ó ṣàfihàn ìtẹ́wọ́gbà àti wípé óún ìṣerẹ́gí tàbí ìṣedéédé wà fún àìsedéédé tîkì. Wíwo àwòṣe ìtẹ́wọ́gbà leè fa àdínkù bá èyí ìpanilára tàbí wàhálà tí ó sì fi ààyè gba àwọn ọmọ ilé ìwé tóní TS láti kọjú mọ́ ètò ẹ̀kọ́ wọn dáadáa Dípò ju ki won ní ìbìnújẹ́ lórí àìsedéédé tîkì.
- Lóye nípa wàhálà tó n fi kún àwọn àmì náà. Ìdánwò àti àwọn ìfarahàn gbogbo máa n fà àfikún bá wàhálà. Àwọn Ìfarahàn leè nílò àtúnṣe àti ìdánwò náà leè nílò láti ṣeé ní agbègbè tó yàtọ̀ tó sì jẹ́ àṣírí.
- Ṣètò àwọn ìrétí tí ó yẹ àti kí o pèsè àlàyé iṣẹ́ ṣíṣe kíkún láti dín àníyàn kù.
- Ṣàyẹ̀wò pẹ̀lú olùpiyamọ ní ilé ẹ̀kọ́ rẹ láti pinnu irú àwọn ibùgbé àti àtúnṣe ètò ẹ̀kọ́ tí a ti fọwọ́ sí fún àwọn ọmọ ilé ìwé. ADA ní o nílò ilé ìwé gíga nla láti ṣe ètò ilé ìgbé àti láti ṣe àtúnṣe fún àwọn akẹ́kọ̀ọ́ tóní àlébù. Àwọn ibùgbé fún àwọn ọmọ ilé ìwé tóní TS lè ṣe ìrànwọ́ láti dín àníyàn ṣíṣe kù, ṣaáyan ìṣòro ìkòwé àti wípé kí o sì ṣe ìwúrí fún gẹ́gẹ́ bí ẹ̀bùn fún àkókò tí wọ́n lò ní ìgbà tí wọ́n ní ìrírí àìsedéédé tîkì àti ìdínkù rẹ̀.



7__ToolKit12pagerEducatorFinal2020_YO.indd 10 6/9/2022 3:07:42 p. m.

## ÀWỌN ÌPÈNIJÀ TÓ F'ARA PẸ́ TS TÍ Ó WỌ́PỌ̀: ÀWỌN IPA OLÙKỌ́ ÀTI ALÁTÌLẸ́YÌN ÒṢÌṢẸ́

| | OT | SLP | C | SP | PL | N | T | CT/ RT | SE | C&B | P/A | Behav |
|---|---|---|---|---|---|---|---|---|---|---|---|---|
| Àwọn ìṣe ìgbéayé ojoojúmọ́ | • | • | • | • | • | • | • | • | • | | | • |
| Àníyàn | • | • | • | • | • | • | • | • | • | • | • | • |
| Àwọn ẹ̀rọ ìrànwọ́ | • | • | | • | | | • | • | • | | | |
| Àkíyèsí | • | • | • | • | | | • | • | • | | • | • |
| Ìṣòro ìpalára | • | • | • | • | • | • | • | • | • | • | • | • |
| Àìlèkọ̀wé/kíbọọ̀dù | • | | | • | | | • | • | • | | • | |
| Àìnídìwọ́ọ́ | • | • | • | • | • | | • | • | • | • | • | • |
| Iṣẹ́ alábòjútó | • | • | • | • | | | • | • | • | | • | • |
| Ṣíṣe ǹkan lójijì | • | • | • | • | • | | • | • | • | • | • | • |
| Àwọn Àlébù èdè sísọ | • | • | • | • | | | • | • | • | | • | • |
| Àwọn ìhùwàsí aláìní ìjánu | • | • | • | • | • | • | • | • | • | • | • | • |
| Ètò | • | • | • | • | | | • | • | • | | • | • |
| Kíkàwé pẹ̀lú òye | • | • | | • | | | • | • | • | | • | • |
| Ìgbésókè ọpọlọ | • | • | • | • | | • | • | • | • | • | • | • |
| Àwọn àmì tí ṣe pàtàkì | • | • | • | • | • | | • | • | • | • | • | • |
| Ìmọ́tótó oorun | • | | | | | • | | | | | • | |
| Ìbáraẹnisọ̀rọ̀ l'áwùjọ àti àwọn ọ̀dọdo | • | • | • | • | • | • | • | • | • | • | • | • |
| Ìkálòlò | | • | • | | | | • | | | | • | • |
| Àwọn iṣẹ́ ọwọ́ | • | • | • | • | • | | • | • | • | | • | • |

OT = Dókítà ìlera lẹ́nu iṣẹ́

SLP = Oníṣẹ̀gùn èdè ọ̀rọ̀

C = Olùdámọ̀ràn

SP = Onímọ̀ ìjìnlẹ̀ nípa ọpọlọ tí ilé ìwé

PL = Ọgá ilé ìwé

N = Nọ́ọ̀sì

T = Olùkọ́

CT/RT = Olùkó ni olùdámọ̀ràn/olùkọ́ni tí ohun àlùmọ́nì

SE = Olùkọ́ni ètò ẹ̀kọ́ tó ṣe pàtàkì

C & B = Olùrànlọ́wọ́ ilé oúnjẹ àti àwọn awakọ̀ akéro

P/A = Aláìkọ́ṣẹ́mọṣẹ́/Olùrànlọ́wọ́

Behav = Onímọ̀ nípa ìhùwàsí

## ÀWỌN ÌBÉÈRÈ TÍ A MÁA N BÈÈRÈ LỌ́WỌ́ ÀWỌN OLÙKỌNI

**1. Njẹ́ àwọn ètò tó dá lórí àbájáde nkàn lè ran ọmọ ilé ìwé lọ́wọ́ láti lè ti ilé ìwé lẹ́yìn lọ́rí ìkápá tîìkì ní iyàrá ìkẹ́kọ̀ọ́?**
*Ìjìyà àti èrè ní kí ṣe ìrànwọ́ fún àwọn ọmọ ilé ìwé, nígbàtí àwọn àmì wọ́n dálé lórí ìwúrí ọpọlọ tí koy sí si ní ìkápá. Fún díẹ̀, kíkópa tàbí rí retí nínú oore iṣẹ́ ṣíṣe yóò dínkù àwọn ìròrí ọpọlọ jọjọ eléyìí tí a lè lò mọ́ ipá látí se ìkápá àwọn àmì náà.*

**2. Ọ̀nà wo ló da láti fí wò àwọn àmì TS yìí kì àba leè pèsè àwọn àtìlẹ́yìn tó tọ́, Dípò ìlò ìjìyà.**
*Àwọn àmì TS ní a gbọ́dọ̀ wò gẹ́gẹ́bí àìlọdéédé àwọn ìwúrí ọpọlọ, eléyìí to fara pẹ́ ìwúrí láti yún ojó ìta tàbí egbò finfin. Nípa yíyún ojú títa yìí, ara leè tùù èèyàn nígbà náà àti fún ìgbà náà. Ṣùgbón, yíyún yìí yóò tún padà wá lẹ́yìn ìgbà díè. Ní àfikún, àmì TS tó wọ́pọ̀ ní ójẹ́ aláìnídíwọ́, eléyìí tó lòdì àmì ìṣòro aláìnídíwọ́ pàtàkì, àwọn ìhùwàsí sí tí ohùn tàbí aláfojúrí, àti àwọn ìmọ̀lára sí àyíká ilé ìwé. Aláìnídíwọ́ ló fi kún àṣìtúnmọ̀ àwọn ọmọ ilé ìwé Ṣíṣe àtìlẹ́yìn fún àwọn ọmọ ilé ìwé aLáti ṣàgbékalẹ̀ àwọn ọgbọ́n àti ìmọ̀ láti ṣe ìtọ́jú àwọn ìpènijà tó pọ̀ díẹ̀ síi ní ó múná dóko ju ìjìyà lọ fún àwọn àmì àṣìtúnmọ̀ ọpọlọ nlá tó lè yìí.*

**3. Ṣe óyẹ kí wọn lè gba ọmọ ní ìyànjú láti lè dín àìsedéédé tîìkì kù bí?**

*Rárá,**m áṣe lọ́wọ́**nínú àdínkù àìsedéédé tîìkì. Àdínkù tic àti àwọn àmì yókù ní ọ́fẹ́ agbára àti àkíyèsí tó pọ̀ gan. Àdínkù tîìkì ní ó lè dín agbára tàbí ipá tí a nílò láti ṣe àkíyèsí àti píparí àwọn iṣẹ́ ṣíṣe kù. Nígbàtí àwọn ọmọ ilé ìwé bá n ní ìdójútì láti ọwọ́ àmì yìí, àwọn náà ni wọn yóò fi Gbogbo ìgbà gbìyànjú láti ṣe àdínkù tîìkì ní ọwọ́ ara wọn ní ìgbà tó bá ṣeéṣe fún wọn.*

**4. Àwọn ní àwọn àìṣedéédé tí óún yọ àwọn ọmọ ilé ìwé lẹ́nu tó wọ́pọ̀?**
*Nígbàtí ọmọ ilé ìwé kọ̀ọkan yàtọ̀ sí ara wọn, àwọn àìṣedéédé tó jọ ara wọn leè wo. Àwọn àìṣedéédé tó jọ ara tó wọ́pọ̀ náà ni ìhùwàsí oní gìrì aláìní ìjánu, àìlèkọ̀wé, àníyàn àti ADHD. Àwọn Àlébù Iṣẹ́ alábòjútó, àlébù ìbáraẹnisọ̀rọ̀ l'áwùjọ àti àlébù ọpọlọ náà ni wọ́n wọ́pọ̀.*

**5. Ṣe àwọn ọmọ ilé ìwé n da ọwọ́ rú nígbà tí wọ́n bá nṣe ìfilọ̀ lábẹ́ èémí wọn tàbí gbìyànjú láti lò àìṣedéédé tic gẹ́gẹ́bí àwáwí asán láti má ṣe iṣẹ́ náà bí?**
*Kíkùn tàbí sí sọ̀rọ̀ lábẹ́ èémí èèyàn náà ní ọ̀nà ìmọ̀ tí ó ṣeéṣe láti ṣe ìtẹ́lọ́rùn ìwúrí ní ọ̀nà tí kò fi ní jẹ́ ìbínú tàbí da nkàn rú. Nílò tîìkì gẹ́gẹ́ bí àwáwí asán Ní kò wọ́pọ̀; ṣùgbọ́n, wọ́n ní àfikún àwọn ìgbà wàhálà, tó n yọrí sí lílo àṣìtúnmọ̀ ìwúlò wọn gẹ́gẹ́bí àwáwí. Nítorí náà, ó jẹ́ nkàn ọgbọ́n láti ṣe àkíyèsí nígbà tí àwọn eléyìí bá ṣẹlẹ̀ láti ṣe ìpinnu irúfẹ́ àwọn àlébù ìmọ̀ ní oun tó n ṣe ìdásí tábí ìdíwọ́ àti láti ṣàgbékalẹ̀ fún àwọn olójúànú àtìlẹ́yìn kí àfikún àwọn àmì tàbí ìyẹrafún ní kò má bà wúlò.*

**6. Ṣé ó se ìrànwọ́ láti pèsè àwọn ìsinmi nígbà tí ọmọ ilé ìwé kan tóní TS bá ní àìsedéédé tîìkì?**
*Ṣíṣe àwọn ìsinmi leè jẹ́ ìrànlọ́wọ́ fún n àwọn ọmọ ilé ìwé kan ṣùgbọ́n jẹ́ oun tó burú jáì fún àwọn míràn. Óleè ṣe ìrànwọ́ fún àwọn akẹ́kọ̀ọ́ náà láti mọ wípé òun ní àsàyàn láti kúrò nínú ìyárá ìkẹ́kọ̀ọ́ fún ìgbà pérété, gẹ́gẹ́ bí ó tín ṣe àdínkù àníyàn níní ìmọ̀lára “wíwà ní àhámọ́”. Ṣùgbón fún àwọn ìyókù, gbígbà ní ìyànjú láti kúrò nítorí àìṣedéédé tîìkì leè má ránṣẹ́ wípé àìṣedéédé tîìkì jẹ́ oun ìdójútì Dípò rírí wọn gẹ́gẹ́bí ọ̀rọ̀ “ódáa” fún ọmọ ilé ìwé tóní TS.*

**7. Ṣe àwọn àìṣedéédé tic ma n ba àwọn ọmọ ilé ìwé yókù jẹ́?**
*Ódá lé lórí bí àwọn olùkọ́ bá ṣe fèsì sí àìṣedéédé tic àti bóyá ati kọ́ àwọn akẹ́kọ̀ọ́ yòókù nípa TS. Ní ọ̀pọ̀ àwọn ìgbà, tí olùkọ́ bá gbà, tó sì mójú kúrò lára àìṣedéédé tîìkì náà, gẹ́gẹ́bí a ṣe n mójú kúrò lára àwọn ohùn yìí (àpẹẹrẹ ẹ̀rọ ìgéko, bààlú, ṣíṣe èsúkè, wí wú ikọ́, àti bẹ̀ẹ̀bẹ̀ẹ̀ lọ), àìṣedéédé tîìkì máa n ṣe àdínkù àti àwọn akẹ́kọ̀ọ́ yòókù ní yóò kọ̀ọ́ láti gbà wọ́n àti láti mójú kúrò lára wọn. Fún ẹ̀kúnrẹ́rẹ́ àlàyé àti ohùn àlùmọ́nì lórí kíkọ́ àwọn akẹ́kọ̀ọ́ nípa TS, o leè kàn sí ìtàkùn àgbáyé tí TAA tàbí kí ó pé TAA. Àtẹ̀jáde tó pegedé kàn wà lórí ìtàkùn àgbáyé TAA tí a pe àkórí rẹ̀ ní, kíkọ́ àwọn akẹ́kọ̀ọ́ nípa àìléra* Tourette Syndrome*. Ní àfikún, o leè bèèrè fún àfihàn nípasẹ̀ Èto Asojú Àwọn Ọ̀dọ́, eléyìí tó ṣàkójọ àwọn ọ̀dọ́ tí a tí kò láti pèsè àwọn àfihàn lórí TS.*

**8. Kílódé tí ó jẹ́ pé àwọn ọmọ ilé ìwé kàn máa ni àwọn àmì yìí dáadáa ju àwọn kíláásìì kọ̀ọkan ju àwọn ìyókù lọ.**
*Nígbà tó jẹ wípé àníyàn má n mú àfikún bá àwọn àmì, àwọn tic to tí kún leè ṣàfihàn àníyàn ní àwọn ìyárá ìkẹ́kọ̀ọ́ eléyìí tí ìpènijà rẹ̀ o pọ̀ tàbí nínú eléyìí àfikún wàhálà wà. Ó le jẹ́ wípé ìyárá ìkẹ́kọ̀ọ́ kan pàtàkì ní o tí di àyíká tó láábòò láti ní àìsedéédé tîìkì. Àwọn ìdí míràn leè jẹ́ nítorí àkókò, bí àwọn àmì ṣe n pọ̀ pẹ̀lú ebi, ní òpin ọjọ́, tàbí lẹ́yìn tàbí nígbà wàhálà tàbí èrò tó ga.*

**9. Kíni ìdí tí ó ṣe jẹ́ ìrànlọ́wọ́ ni láti pèsè ibi ọ̀tọ̀ fún akẹ́kọ̀ọ́ kan tóní TS láti ṣe àwọn ìdánwò?**
*Níwọ̀n bí ìpakúpa tîìkì nílò agbára àti àfiyèsí, àwọn akẹ́kọ̀ọ́ lọ́pọ̀ ìgbà yóò gbìyànjú láti tẹ tîìkì mọ́lẹ̀ lákòókò ìdánwò kí wọ́n má bàa kó àwọn ọmọ kíláàsì wọnpin. Ní ibí ìkọ̀kọ̀, akẹ́kòó náà lè fojú sí ìdánwò náà Dípò àìsedéédé tîìkì rẹ̀.*

**10. Njẹ́ níní ìbínú kúkúrú leè tan mọ́ àìléra Tourette Syndrome bí?**
*Bẹ́ni, fún àwọn àlàyé tí ó pọ̀. Bíbá TS fínra ní ó jẹ́ nkàn ìdójútini àti èyí tó n máa n ló èèyàn ní agbára. Àwọn ọmọ ilé ìwé pẹ̀lú ìṣòro Aláìnídíwọ́ lè máa tiraka pẹ̀lú ìṣòro lórí àwọn ìmọ̀lára rẹ̀. Ní àfikún, púpọ̀ nínú àwọn àìṣedéédé tó wọ́pọ̀ yìí bíi ìdàgbàsókè ọpọlọ, ìṣiṣẹ́ ló àwọnrí ìdádúró, iṣẹ́ alábòjútó, OCD àti ADHD leè fi kún ìfòòró, tó yọrí sí ìbínú.*